# KÍKAN JESU MỌ́ AGBELEBU
## Matteu 27:27-56
## ẸKỌ 64 – FUN AGBA

**Akọsori: "Gbogbo wa ti şina kirikiri bi agutan, olukuluku wa tẹ̀le ọ̀na ara rẹ̀; OLUWA si ti mu aişedede wa gbogbo pade lara rẹ̀" (Isaiah 53:6).**

**I Wọ́n Huwa Abuku si Jesu**

1. Awọn alaşẹ fi aşọ òdòdó wọ Jesu, lati kẹgan Rẹ̀, Matteu 27:27, 28; Luku 23:11; Johannu 19:1, 2
2. Wọn fi ẹgun de E ni ade lati fi şẹsin, Matteu 27:29; Luku 22:63
3. Jesu fara gba iya ti o buru jai, Matteu 27:30, 31; Isaiah 53:3-5; 50:6; Heberu 2:10
4. Nitori o rẹ Jesu a fi agbara mú Simoni ara Kireni lati rù agbelebu Rẹ̀, Matteu 27:32; Luku 23:26; Marku 15:21
5. A mu Un lọ si ibi ti wọn gbe ti kàn An mọ́ agbelebu, Matteu 27:33, 34; Johannu 19:17

**II Jesu Lori Agbelebu**

1. Wọn gba aşọ ileke Rẹ̀ gẹgẹ bi Iwe Mimọ́ ti wi, Matteu 27:35, 36; Orin Dafidi 22:18; Johannu 19:23, 24
2. Pilatu kọ akọle sori agbelebu Jesu, Matteu 27:37, 38; Marku 15:26; Luku 23:38; Johannu 19:19
3. Awọn eniyan fi Ọmọ Ọlọrun şe ẹlẹya, Matteu 27:39-44; Marku 15:29-32; Isaiah 53:12
4. Okunkun de ni ọsán gangan, Jesu si sọrọ lati ori agbelebu, Matteu 27:45-49; Orin Dafidi 69:21; Marku 15:33-36
5. O sọ ọ̀rọ Rẹ̀ ikẹyin, O si kú, Matteu 27:50; Marku 15:37; Luku 23:46; Johannu 19:30

**III Awọn Işẹ-Iyanu ti o Şẹlẹ ni akoko Ikú Kristi**

1. Aşọ ikele Tẹmpili faya, Matteu 27:51; Marku 15:38
2. Isẹlẹ sẹ̀, Matteu 27:51
3. Ọpọlọpọ iboji awọn eniyan mimọ́ şi silẹ, Matteu 27:52, 53
4. Balogun ọ̀rún şe ijẹwọ nla, Matteu 27:54; Marku 15:39; Luku 23:47, 48
5. Awọn obinrin oloootọ́ tẹle Jesu, Matteu 27:55, 56; Marku 15:40, 41.

## ALAYE

**Etutu Nì**

Iwe Mimọ́ kọ́ ni ni ẹkọ ti Etutu yékéyéké o si tun fi idi rẹ̀ mulẹ ninu Isaiah 53:5-7; Matteu 20:28; Johannu 1:29; 1 Johannu 1:7; 2:2; ati ọpọlọpọ ẹsẹ Iwe Mimọ ni o şe alaye ifi rọpò ati etutu yekeyeke ni ọ̀na ti o yanju jù lọ ti a le fi ẹnu sọ. Dajudaju otitọ ni pe ikú Ọmọ Ọlọrun lori igi Agbelebu ni Kalfari jẹ́ etutu fun ẹ̀şẹ awọn eniyan; şugbọn ifi-rọpo ati etutu yii jẹ́ anfaani fun kiki awọn eniyan ti wọn ba ronupiwada tọkantọkan ti wọn si yipada patapata kuro ninu gbogbo ẹ̀şẹ wọn. Ọmọ Ọlọrun jiya ki i şe pe ki a ba le wà ninu ẹ̀şẹ sibẹ şugbọn ki a ba le gbé lai si ẹ̀şẹ (Romu 6:1, 2, 6). Idi rẹ̀ ti etutu yii fi jẹ ọranyan ni a fi hàn (Esekiẹli 18:4; Romu 5:12); lai si eyini ikú nipa ti ẹmi daju. "Kristi ti kú nitori ẹ̀şẹ wa gẹgẹ bi iwe-mimọ́ ti wi" (1 Kọrinti 15:3).

**Iwọsi ti Wọ́n Şe si Kristi**

A fi Jesu şe ẹlẹya, a fi şẹsin, a si kẹgan Rẹ̀ ni ọna ti o buru ju lọ lati ọwọ́ awọn eniyan ki a to kan An mọ́ agbelebu, şugbọn O jiya O si fi ara da gbogbo nnkan wọnyii ni ipò wa. O ti bá Baba Rẹ̀ dá majẹmu kan lati jẹ onigbọwọ ati ifi-rọ́po fun ẹni ti o jẹbi – lati kú oloootọ fun alaişootọ. Fun ijiya ikú a bi I ninu obinrin (Galatia 4:4), "o si di ara, on si mba wa gbé" (Johannu 1:14), nigba ti O si gbe awọ̀ awa eniyan wọ̀ ki i şe kiki etutu fun ẹ̀şẹ wa nikan ni O şe, şugbọn fun isọdimimọ́ ati iwosan nipa agbara Ọlọrun.

**Jesu Lori Agbelebu**

Laaarin idojukọ ti o pọ̀ rekọja ati awọn ohun ti o le mu ipaya ailefẹnu sọ ba eniyan, O n wá awọn ti o sọnu sibẹ titi a fi kàn An mọ́ agbelebu. "O wu OLUWA lati pa a lara" O si ti fi "ẹmi rẹ̀ şẹbọ fun ẹ̀şẹ" (Isaiah 53:10). Iku Kristi mu idajọ otitọ şẹ, ki Ọlọrun ba le jẹ olódodo ati oludare ẹniti o gbà Jesu gbọ́" (Romu 3:26). Nitori idajọ ti o yẹ ki a gbà fun ẹ̀şẹ wa ni ikú ati iparun ayeraye, nipasẹ iku Jesu ni a si n dá wa lare. Ninu I Johannu 2:2; 4:10 ati Romu 3:25, a ri ifidimulẹ siwaju si i pe ikú Jesu jẹ́ ikú ifi-rọpo. Ede Griki ti a lò ninu awọn itọka si ẹsẹ ọrọ meji akọkọ ni **"hilasmosi,"** ati ni ti ikẹyin **"hilasterioni."** Itumọ ọrọ ti o kẹyin yii ni itẹ-aanu. Ọrọ mejeeji yii ti inu ọrọ yii **"hilaskomai"** jade, itumọ eyi ti i şe **"lati şe ilaja," "lati şetutu"** tabi **"lati yí ibinu ẹni ti a şẹ̀ kuro."** Awọn ẹsẹ ọrọ ti o tọka Kristi gẹgẹ bi etutu tọka si ijiya ati iku rẹ̀, gẹgẹ bi ọna ti Ọlọrun le gba lati fi aanu hàn tabi ki O şe oju rere fun awọn ẹlẹşẹ. Nitori naa "laisi itajẹsilẹ kò si idariji" (Heberu 9:22). Ọmọ Ọlọrun ko tun ni lati pada lẹẹkan lọdun, gẹgẹ bi olori alufaa ti o wọ ibi mimọ́ pẹlu ẹ̀jẹ ti ki i şe ti rẹ̀ (Heberu 9:25), şugbọn "Kristi pẹlu

lẹhin ti a ti fi rubọ lẽkanṣoṣo lati ru ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ.," O si ti lọ "si ọ̀run pãpã, nisisiyi lati farahan ni iwaju Ọlọrun fun wa" (Heberu 9:24).

A ri ẹri ti o daniloju fun iwosan ninu Etutu naa. Ninu Numeri 21:8, 9, a kà pe Ọlọrun paṣẹ fun Mose pe ki o ṣe ejò amubina ki o si gbe e soke ki awọn Ọmọ Israẹli ti n ṣaisan ba le wò ó ki wọn si sàn. Awọn eniyan n kú lọ nigba naa, awọn ti wọn si kọ̀ lati wo ejò naa si kú. Iṣẹlẹ yii jẹ apẹẹrẹ igbala ati iwosan gẹgẹ bi a ti pese rẹ̀ silẹ fun wa ninu Etutu naa. "Bi Mose si ti gbé ejò soke li aginjù, gẹgẹ bẽli a kò le ṣe alaigbé Ọmọ-enia soke pẹlu" (Johannu 3:14).

A gbé E soke fun igbala wa, isọdimimọ́ wa, ati iwosan wa. Nigba ti a ba gboju wa soke si Kristi Ẹni ti o ru ẹ̀ṣẹ wa lori agbelebu a ri iwosan gbà nipasẹ Etutu naa. "Nipa ìnà ẹniti a mu nyin larada" (1 Peteru 2:25), itumọ eyi ni pe Jesu jiya nínà ikà ti o pọ̀ to bẹẹ ti ẹ̀jẹ fi n tú jade lati ẹ̀yin mimọ́ Rẹ̀ wa; ẹ̀jẹ ni ti a ta silẹ ni o n mu iwosan wá. Nigba ti a ba n fẹ iranlọwọ a le bojuwo ẹyin wò Kalfari ni igbagbọ́, Ọlọrun yoo si wo ara wa sàn.

Ninu Heberu 13:12, a kà pe, "Jesu pẹlu, ki o le fi ẹ̀jẹ ara rẹ̀ sọ awọn enia di mimọ́, o jiya lẹhin bode." Ọpọlọpọ ni o n wi pe kiki idalare nikan ni Oluwa rá fun wa ni Kalfari. Ṣugbọn O ṣe iṣẹ aṣepe ti ẹkún rẹrẹ́ igbala. Ohun ti a n pè ni ẹ̀kún igbala ni gbogbo iriri ti a n rí gbà lati igba ti Ọlọrun ba mú ki a ni idalẹbi ọkàn ti O si mú wa wá sọdọ Kristi titi a oo fi mú wa lọ pade Rẹ̀ ni ofurufu. Isọdimimọ́ jẹ́ ọranyàn lati ni ninu ọkàn; nitootọ, "eyi ni ifẹ Ọlọrun" (1 Tẹssalonika 4:3). A ni lati ni iriri igbesi-ayé isọdimimọ́ bi bẹẹ kọ́ a kò ni ẹ̀tọ́ lati maa reti lati wà pẹlu Oluwa. Heberu 12:14 sọ fun wa pé lai si iwa mimọ́ yii a ki ó tilẹ rí Oluwa, ki a má ṣẹ̀ṣẹ̀ sọ ki a wà pẹlu Rẹ̀ laelae. Eyi ni ẹ̀kún igbala ti a rà fun wa lori Agbelebu ti Kalfari: idalare nipa igbagbọ́; isọdimimọ́, iriri ti ó daniloju ti iṣẹ́ oore-ọfẹ keji; ati iwosan nipa agbára Ọlọrun fun ara wa nigba aisan.

**Awọn Iṣẹ-Iyanu Ti o Ṣẹlẹ̀ Ni Wakati Ti Kristi Kú**

Ọlọrun fi ẹri fun ni siwaju si i nipa pé Jesu jẹ́ Ọmọ Ọlọrun nigba ikú Oluwa wa. Aṣọ ikele Tẹmpili fàya lati oke dé isalẹ eyi ti o n fi hàn pé ọ̀na ibi mimọ́ julọ ti ṣí silẹ nipa Ẹjẹ Jesu (Heberu 10:19, 20). Iboji ọpọlọpọ awọn eniyan mimọ́ ni ó ṣí silẹ. Awọn nnkan ti o ṣẹlẹ tilẹ mu ki balogun ọ̀rún jẹri iyanu bayii pé, "Lõtọ Ọmọ Ọlọrun li eyi iṣe."

**AWỌN IBEERE**

1. Njẹ wọ́n aṣọ òdòdó wọ Jesu lati bu ọlá fún Un?
2. Taa ni ẹni ti ó ran Jesu lọwọ lati ru agbelebu?
3. Ki ni ohun ti wọn kọ gẹgẹ bi akọle ti ó wà lori agbelebu ti wọ́n fi Jesu kọ́ si?
4. Ki ni iwa awọn Ju si Jesu paapaa ni akoko irora nla ti O là kọja?
5. Ki ni idahun awọn Ju si Pilatu nigba ti ó n wá ọna lati dá Jesu silẹ?
6. Darukọ awọn iṣẹ-iyanu ti o ṣẹlẹ ni akoko ti Ọmọ Ọlọrun kú?
7. Ki ni balogun ọrun wí?
8. Ki ni ikú Jesu lori agbelebu já si fun ọ?